4 DEC 1965


# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI · GBOGBO LA WA

No 1,571 SATURDAY NOVEMBER 27, 1965 (2D)


## Awon Ara Ilu Ewu Wa Lẹhin Adegbenro

OSECDI— Ninu irohin kan to de ile iṣẹ wa ni ọsan ọjọ Ẹti ti iṣe Ọjọ kẹrandinlọgbọn osu yi ni ọkan ninu uwọn Aṣọju ọmọ ẹgbẹ Afẹrifẹre ni ilu Ewu Ọgbeni Yisa Oseni ti ni awọn enia ilu Ewu ni agbegbe Oshodi kan saara si Adele Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre Alhaji D. S Adegbenro lori akitiyan rẹ lati igbati Olori ẹgbẹ na Oloye Awolọwọ ko ti si nile.

Ọgbeni Oseni tun dupẹ lọwọ Alhaji D. S Adegbenro fun wahala rẹ lati igbati nwọn ti ṣe idibo si Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ni Ojọ kọkanla oṣu kẹwa ọdun yi.

O tun ṣe alaye pe ki Alhaji D. S Adegbenro ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ maṣe boju wo ẹhin rara ninu iṣẹ rere wọn ti nwọn nṣe ati pe gbogbo ọmọ ibilẹ ilu Ewu to nṣe Afẹnifẹre lo ni igbẹkẹle ninu awọn ti nwọn duro lẹhin wọn gbọnin gbọnin.

Ọgbeni Yisa Oseni tun tọka si irohin kan to jade ninu iwe Irohin Imọlẹ ti ọjọ kọkandinlogun Oṣu yi ti o sọ wipe on lo ko ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) wọ ilu Ewu.

Ọgbeni Oseni tun ṣe alaye pe eyi ki iṣe bẹ rara bikoṣe wipe gbogbo ọrọ ti o jade ninu iwe irohin na loruko on ni ki iṣe otito.

O tun ṣe alaye pe eniti o sọ ọrọ irọ bayi ko fi Orukọ ara rẹ si ati eyi ti fi hna pe irọ patapata ni ọrọ to wa ninu iwe na.

WO OJU EWE KẸFA

# EGBE ALAKUKO YO WACHUKU KURO L'ẸGBẸ!

ẸNUGUN:— "Ọjọ npofin wayi O, Ọjin fẹ fi igan ta Ọnọ rẹ."

A gbọ yanu ni Irohin ti o kan gbogbo enia ku, yika gbogbo Origun mẹrẹrin Orile ede Naijiria titi de Oke Okun nigbati awọn enia gbọ Irohin wipe, ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ti yọ Dokita Jaja Wackuku, Minista Alamojuto eto igbokegbodo Ọkọ Ofurufu fun Apapọ Ijọba Naijiria kuro ninu ẹgbẹ wọn.

Ọgbeni F r e d. McEwen, akọwe agba ẹgbẹ Alakukọ ṣe alaye fun Oniwe Irohin wa ni Ẹnugun ni ana Ọjọ Eti ti iṣe Ọjọ kẹrinlelogun Oṣu yi wipe, Oti to Ọjọ mẹta ti awọn Ọmọ ẹgbẹ na ti nṣe ipade lori awọn iwa na ti nṣe ipade lori awọn iwa kan ti Ọgbeni McEwen sọ wipe iwa ti ko dara ni Jaja Wachuku nhu ninu ẹgbẹ na ti awọn si nsọ fun un, sugbọn ti ko gbọ bẹẹni ko si tun si ireti pe yio yi iwa na pada.

Ọgbeni McEwen sọ wipe o ṣe enia ni ọpọlọpọ aanu lati ṣe ifilọ ọrọ yi fun gbo gbo enia gbọ wipe awọn yọ Dokita Jaja Wackuku kuro ninu ẹgbẹ paapa julọ ni asiko yi

O wa ṣe alaye wipe lati bi ọjọ meta ṣẹhin wa ni ni awọn ọmọ ẹgbẹ na ti nwon wa ninu Igbimọ Amuṣẹṣẹ ẹgbẹ na ti nṣe ipade lori ọrọ yi.

O tun sọ pẹlu wipe lati bi ọjọ mẹta ni awọn ti nṣe akiyesi iwa gbelegbi da ti Dokita Wachuku ti nhu larin ẹgbẹ sugbon nigba ti iwagbelegbida yi farahan si awon ọmọ ẹgbẹ lẹsẹkẹsẹ ni nwon ti sare pe Dokita Wachuku ni enu ireti pe bi awon ba tete sọ ọrọ na ni eti rẹ ti awon si fi asiṣe rẹ han an yio tete yipada lati tun awọn asiṣe rẹ ṣe

Ṣugbọn gbogbo bi awọn ti ṣe joko ti gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ti nwọn wa ninu Igbimọ alabẹṣekele ati Amuṣẹṣe ṣe sọrọ na to, Dọkita Wachuku ko yipada ninu gbogbo iwa yi.

Ni ibẹrẹ oṣu yi ni Dọkita Jaja Wachuku ọ ọgbẹni Kofo Blackson, ọkan ninu awọn Alakoso ile iṣẹ ọkọ ofurufu, ti Minista na si le



**Dokita Jaja Wachuku**

Minista Alamojuto eto Igbokegbodo Ọkọ Ofurufu Fun ApapọIjọba Naijiria

Alakoso na sọnu.

Ọgbeni McEwen so pe nigbati awọn gbọ irohin yi, o ya gbogbo enia lẹnu lati gbo oro na nigbati awon si gbo ni awon ba sare pe Dokita Wachuku lati wadi oro na lẹnu rẹ bi o ba tise jẹ.

Nigbati o de awon bere oro lowo awon mejeji ohun ti o fan ki nwon si gbo oro na.

Nigbati awọn mejeji sọ ti ẹnu wọn awọn si da ẹjọ na si otun awọn tun da si osi awọn si pari ọrọ na fun wọn bi o ti tọ ati bi o si ti yẹ.

Lẹhin eleyi ni awọn wa paṣẹ pe nigbati awọn ti sọ ọrọ na tan fun wọnyi ki, Dokita Wachuku gba Ọgbẹni Kofi Blackson pada si aye rẹ ninu ile na.

Ṣugbọn fun iyalẹnu awọn ati gbogbo enia awọn ko gbọ lati igbana ki Dokita Wachuku gba Ọgbẹni Kofi Blackson pada bẹẹsi ko si tun ba wọn sọ nkankan.

Ikede awọn Ọmọ ẹgbẹ na sọ wipe, nigbati Dokita Wachuku fi wa ni ipo Minista Alamojuto eto awọn ilẹ Okere fun Apapọ Ijọba Naijiria, bayi ni Minista na ṣe aṣe, ti o nlọ ṣe awọn nkan ti Apapọ Ijoba lodi si ti nwon ko si tun fẹ pẹlu

Ohunti Dokita Wachuku ṣe nigbana jẹ ohun ti o buru ti ko si tun ṣe gbo si eti, ani, loju awon Orile - ede Okere ti nwon ko mo Naijiria daada nigbana, ti nwon si lero pe, Apapo Ijoba lo fi iṣẹ na ran Dokita Wachuku,

Lati igbayi ni ẹgbẹ Alakukọ ti nkilọ fun Dokita Wachuku, ti nwọn si ni ero pe yio gbọ gbogbo imọran ti nwọn nsọ fun un ati awọn ohunti nwọn nso fun: "ṣugbọn kaka ki o ṣan fun Iya aje, o tun nfi ọmọ rẹ bi obinrin ẹiyẹ nyi lu ẹiyẹ". sugbon oro na ko tilẹ tun wa dinku mo, ṣugbon apele lo tun apele.

Awon omo egbe na ni nitori ohunti Dokita na ṣe ni gbati o wa ni ipo minista Alamojuto eto awon Ile-Okere ni ko jẹki Apapo Ijob. tun ya ann si aye na mo nisisiyi ti nwon si fi yi ipo minista re sile ti nwọn fi gbe e si minista Alamojuto eto Ọko Ofurufu fun Apapo Ijoba.

Nigbogbo igbati ẹgbẹ Alakukọ si nfi silẹ, ti nwon fi nba Dokita Wachuku sọrọ gbogbo ọrọ ti nwọn ba bai so, ẹkun igba ni nwọn nyi agba po si i Jaja Wachuku si gba imoran na

Akowe ẹgbẹ na ti kowe si Alhaji Tafawa Balewa Alakoso apapọ Ijọba Naijiria wipe ki o tete yara yọ Dokita Wachuku kuro ni aye Minista ẹgbẹ to si yan an si aye ti o wa yi, ẹgbẹ na ti yọ kuro lẹgbẹ won patapata nitori ohunti akọwe ẹgbẹ na pe ni, iwa aigbọran [illegible] ti inu mi ni ngo ṣe eyiti nwọn so wipe Dokita Wachuku nhu si ẹgbẹ won

Awọn kan tun nsọ ninu ẹgbẹ Alakukọ pe bi Alhaji Balewa ko ba le le Dọkita Wachuku kuro ni aye minista to wa yi, a jẹpe ija yio wa larin awọn ọmọ ile Igbimọ aṣofin apapọ Ijọba Naijiria eyiti a ko le sọ ibiti o le yori si lẹhin ọla.

Awọn enia ẹgbẹ kan si nsọ wipe, Balewa ṣenia papọ, ko ni gbọ nibiti yio gbe yọ Dokita Wahuku kuro ni aye

Wo Oju Ewe Kẹfa

# ALAYE ỌRỌ LORI RUDU-RUDU IPINLẸ IWỌ ORUN

Nigbesi aiye ọmọ enia ohun ti a npe ni iyanu ki dopin. Ohun iyanu to wa nilẹ fun ilẹ Najiria loni ni abayọri idibo ni Ipinlẹ Iwọ Orun ti Naijiria. Ki ṣe ohun gbogbo ni o mu iyanu wa. Ti a ba gbọ pe era di erin gannaku ninu igbo lọjọ kan, mọ ro pe eyi yio jẹ ohun iyanu fun ni lati gbọ.



OGBẸNI EYỌ ESUA
Alaga Igbimọ Eto Idibo

Ti a ba si wipe erin di era bakan naa yio ya ni lati gbọ. Bayi ni gbogbo nkan ti a npe ni iyanu yio bẹrẹ.

Lati igbati nwọn ti pari idibo ni Iwọ Orun ni orisirisi iwa ipa ti bẹ silẹ. Bi minista ti nsare fun ẹmi rẹ beni awọn oṣelu na kesẹ le ire fun ẹmi wọn na pẹlu

Alaga ga ni awọn bọrọkinni na ni oya fun igbesi aiye wọn Ako lesọ bi awọn ẹlẹmi kan eyi ni awọn mẹkan na ti ni fi apẹrẹ de ori wọn ki nwọn maba gba ọta ibọn ọlọpa. A kole ma sọbi ofin mariu loru ati ma se inade ita na tun wa

Ofin ma wọde kiri lowọwọ na tun joko nilẹ. Ẹnikẹni to ba ta fele-fele tẹtẹ ofin njẹ olu wa rẹ. Gbogbo nkan wọnyi lonsẹlẹ ti orilu nwo ti Ola oren dakẹ nwo. Kini oma gbo gbo nkan rudurudu wọnyi wa biko se abayọri idibo ti Iwọ Orun

Ni gbọ ti awa ri idi ọrọ nwọnyi; a gbọ wipe ojoro wa ninu idibo Iwọ Orun. N aiye awon baba wa bi enia mi ba nta ayo pọ ti ojoro ba siwa ọlọla ti wọn saba mesọ nipe ki wọn to ayo na le ki awọn atayo wọnyi mata ayo a ta si ọwọ si

Bayi ni won ma pari ọrọ ojoro ni gbo ayo titi. Sugbọn lode oni yi ọrọ ki ti ri bẹ mọ. Gbogbo wa gbọ pe ojoro wa ni u idibo tokọja ni Iwọ Orun. Awọn kan wipe ko si ojoro rara ninu idibo

Ojoro tabi eru wa labi ko si, se awa ri efin iwa bubu-ru ni ode wa kiri; ọrọ yi wa dabi igbati ẹkun wọ ilu ti o gbe ọmọ adẹtẹ. Bi o ti ngbeọmọ yi ha ẹnu to sare lọ ni gbogbo ilu bẹrẹ si yọ ti wọn si njo pe yanmoyanmọ ati orun ku ro larin ilu wọn

Sugbọn nigbati o se ẹkun na tun pada wa gbe ọmọ ọba ilu wa Ariwo ti ẹkun ati ọfọ gba gbogbo ilu kan

Iwa aidogba wa nigba ti wọn ka enia ile Naijiria ọrọ yi fẹrẹ mu ipin ya wa ba orilẹ ede yi

Sugbọn nitori awon ayafẹ Olọrun gbogbo rogbodiyan pari ọro na nipa apaipatan Bayi ni ọra idibo miran yi tun ma wahala wa lati kan bi osu kan abọ

Ninu ọrọ yi Gomina Ila orun sọ otito fun re Nwọn ni ki o pa ẹnu mọ ki o joko jẹ bi omolangi

Ni ọkan bi ọjọ mẹta to kọja Ọgbẹni E. E. Esua tun dide gẹgẹbi alaga gbogbo awọn Oloye alabojuto idibo ilẹ Naijiria.

Gbogbo enia ni o nreti rẹ kio sọrọ ohun ti oju rẹ ri ati ohunti eti rẹ gbọ. Gẹgẹbi alaṣẹ eniti o ni aṣẹ lati la ohun gbogbo ye alaiye.

Gbogbo ohun to mọ gẹgẹbi alaga awọn ala mojuto idibo ti o fẹnu fi lelẹ lori iwa idibo ni wọn ko tele gẹgẹbi o ti yẹ Ọgbẹni Esua ni on ko kọ iwe kan si Gomina Iwọ Orun lori abayọri idibo.

Bakanna ni Ọgbẹni Esua fi ẹ u ba pe awọn iroi miran wati ko yẹki a ti ri iwe idibo ti a si nri wọn o ni iru nkan ba wọnyi ko tọ rara wayi o ni awọn akọwe ko to lati ṣe iṣẹ na

Bayi ni Ọgbẹni Esua sọ awọn ohun to ri ni ọna bi mẹwa, Lẹhin na o tun wa sọ fun ni nipari pe o yẹki tun ofin idibo ṣe ki o si murọrunju ti ati hin wa lọ.

Bi o tilẹ jẹ pe o pẹ ki O. beni Esua sọ ọrọ inu re fun orilẹ Naijiria gbọ nipa idibo yi sugbọn awọn ọjọgbọn aiye sọpe o san ki enia pẹ lati de ibi kan ju ki o ma lọ de ibẹ rara.

Kete ti Ọgbẹni Esua sọrọ rẹ sinu awọn iwe irohin fun araiye ka ni orisirisi awọn ora ọrọ njade si l. Ẹlomiran ba ẹnu ale lu gbogbo ọrọ tamutamu to gbe kalẹ fun alaye tirẹ.

Awọn miran nsọko ọrọ sii, Bi awọn elomiran ti nmọju lori ọrọ yi ni awọn miran na tun kan sara si fun igboya rẹ

Emi papa na kan awọn kan dimọlu lati ṣe ọrọ no fun ibajẹ

Ati pe ọrọ dabi ẹnipe ọgbẹni Esua faramọ ẹya kan jugọkan lo lẹhin na igbati o bere siko awọn oro re sinu iwe si Gomina ko pe awon ti ọgbẹni se alaga fun ki awon jọ se se a ape re lori oro na ki o to ma ko won si ita fun araiye gbọ.

Nitorina awon ọmọ labẹ aga Esua ni ko si otito ninu oro to koso o si Gomina Iwọ orun

Ju gbogbo rẹ lo awọn ọmọ labẹ aga Esua to gaba le lori fun idari apero ati ifi orikori fun ilọsiwaju iṣẹ idibo bu atẹ lu ọrọ rẹ wipe awọn ko faramọ ọrọ rẹ,

Ninu awon to wa lẹhin Aga Esua ni Eni Owo S O Ola Akande Sajo ki a on egbe re to ko ara won jo awon si lodi si oro Esua ni Eni o o S Ola Akande te waya si Esua ti o si dupe pe otito ni oro gbogbo ti o sọ ati pe eru ati ojoro wa ninu idibo iwo Orun to koja yi,

Lehin to ṣo be t n ni awon eghe re ti pin ere ẹke ebu ranṣe si on na pe kosota ni ena na tun so Oro re o enyin omo enia aiye Gomina so won ni ki o pa ẹnu mo, Esua o'ot i soro won ni ki o gbe enu sohun Eni owo

S O Ola. Akande jẹri si ọrọ Esua wọn ni ki o lo di Bibeli rẹ mu ki e ma jẹri otitọ kini ki awa mekun nu yo ṣe?

WO OJU EWE KARUN



OLOLA FADAHUNSI
Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria

LATI OWO

## Alagba S. O. Jaiye

bi Ọgbẹni Esna ni loti to ati lodod o ni eru wa ninu idibo iha Iwọ Orun o ni awọn ọpọlọ nu awọn a amojuto idi bo na ni o fi aye idi se ti a yan wọn si sil; ti wọn ko d to ni ibi aye ise wọn.

Ọgbẹni Esua ni awọn eto miran to wa ti a s sara temi si akọsilẹ rẹ Bi gbogbo enia ti nronu lori ọrọ Ọgbẹni Esua ti won ṣe apẹrẹ lori awọn nkan wọnyi ni awọn ọmọ labẹ aga Esua tun ko ara won jọ pọ lati lodi si ọrọ rẹ, wide awọn ko faramọ gbogbo ọrọ rẹ nitoripe o jowu pe o ba

# Iwe si Olotu Irohin Imole

## Apapo Ijoba O Di Owo Nyin O

Olotu jowo gba mi ni aye die ninu iwe nyin to kun fun ogbon ati oye lati kesi awon olori ile Naijiria ati paapa julo apapo Ijoba Naijiria lati tete se ohunti o to ti o si ye eyiti o le mu ilosiwaju ala fia ati emi gigun ba enyin ti ise Alase Ijoba nipa ohunti o nsele ni Ipinle Iwo Orun Naijiria lori abayori idibo si Ile Igbimo Asofin Ijo a Ipinle Iwo Orun Naijiria to koja lo yi.

Ohunti o nfa isele to nsele ni Ipinle Iwo Orun Naijiria bayi ni aşie otito awa enia Ipinle na nina bi o ti ye ki a se ohunti o to nipa eto abayori ibo ns eyiti o ye ki a so eniti o bori ibo na ki a si fi se ti otito eyiti o le mu alafia ba gbogbo Ipinle Iwo Orun ati paapa julo enyin ti ise olori ile Naijiria.

Inu awa enia Ipinle na yio dun bi enyin ti ise alase orile ede Naijiria ba le dabuo si ohun ti o nsele ni Ipinle na lati jek awon egbe oselu ti gbogbo aiye mo pe o bori ibo nsle wa lori akoso Ijoba Ipinle na.

Olotu mo dupe fun aye ti e gba mi ajinde yio ma je fun yin

Emi ni
Y B Omoshola
AGBADA-BADAGRY

## Agba Idofian O di Owo Nyin O

Olotu:- Inu mi yio dun bi e ba le gba mi ni aye ranpe ninu iwe nyin to nla bi akara gbigbona lati kesi awon Agba ilu Idofian lori iro ti nwon ti npa fun wa ni ilu Ilorin eyiti awa enia ilu Idofian fi nsin ilu Ilorin lati ojo yi ti ko si iranlowo kankan ti Ijoba ibile ilu Ilorin se si ilu wa ati pe o ti to ge e ti o ye ki a gba ara wa kura lowo Ilorin.

Awon alagba lo mo npa lowe pe eniti ko ba gbon ti o ba di eni ogoji odun ko ni gbon titi mo fe ki enyin agba ilu Idofian ronu to ba je enu lo nba nyin o ye ki e so ki e jeki a mo ohun nba nyin leru.

Oye ki e ranti pe ile iwe kan soso ni a ni ilu wa ati pe ko si iranlowo kankan ti o je wipe a ri gba lati ojo yi eyiti o ye ki Ijoba ipinle Ariwa se eto lati ko ile iwe miran fun wa.

E jeki a titori eyi gi imo po lati yan omowe kan ti a o dibo fun ninu idibo to mbo yi ki a si lo fi oruko re sile gegebi Asoju wa ki a si tu san ogorun ponun £100 eyiti a o san sile gege bi owo ti yio san sile ki a to dibo fun.

Emi ni
B, O de
IDOFIAN.

## Enyin Omo Yoruba E Ronu

Olotu Jowo gba mi ni aye die ninu iwe nyin to nta bi akara gbigbona lati kesi awon omo ile Yoruba ki nwon mase sun lo ki e jeki aja fun ohunti ise ti wa eyiti nwon fe ta fun awon Hausa ki esi jeki ale segun ikehin yi nitoripe ele yi ni ireti kansoso ti ani bayi

O ye ki a ranti ohunti oloye Obafemi Awolowo se fun wa ki asi jeki ole jade logba ewon ti owa bayi ohunti ole gbe olori wa ti ise oloye Awolowo kuro logba ewon ni ona bi a o tise dnra lehin Alhji D S Adegbero ti ise Ade le olori egbe olope

Nitoria eyi e jeki se ira ti asiko ti oloye Awolowo nse eto akoso ijoba ipinle iwo Orun nigbati gbogbo nkan ndun fun wa ti ani owo lowo ti asi ni ifokan bale eleyi ni oye ki a tona ki e duro ti Alaji Adegbenro ki olori ile Yoruba le ja po

Emi ni Joseph Olatunji
OLOWA-OMIJO

## Mo Dupe Lowo Awon Enia Oke-Ode

Olotu Jowo gba mi ni aye die ninu iwe nyin to kun fun ogbon ati oye lati dupe lowo awon enia ilu Oke-Ode nwon si wa sibi isinku iya Ogbeni Omo Oba Garuba Maku ni ojo kokandinlogbon osu tokoja lo yi ni ilu Oko-Ode bakanna ni mo ki gbogbo ebi ile iya ni pe e ti iaoju.

Mo tun dupe lowo Oba Oke-Ode, iman ilu awon Oloye ilu ati egbe kobinu-Enikan pelu awon Akowe Ijoko ojo na,

Bakanna ni mo tun ki awon enia wonyi awon bi Suberu Giwa Jimoh Agbole Jimoh oba, Salawu, K A Owolabi A A Kolade Aliu ode Sanni Olabi S Alafin Giwa Bakare Raji A A Bolarinwa ti ile itoju awon alayan oke ode ati Ajide Jimo

Oluwa na yin sifi rere ka gbogbo wa Oluwa yio jeki olukuluku gbehin arugbo re

Olotu mo dupe aye ti e gba mi ajinde yio maje fun nyin oko oba ko ni sa tyin lese o

Emi ni
Omo oba Garuba Maku
Oke Ode


## Iwo Ha Nfe Ile L'Eko Bi

| | |
|---|---|
| Room | £3 |
| Room | £4 |
| Room | £5 |
| Room / Parlour | £6 |
| Room / Shop | £15 |
| Flat (Lagos) | £20 |
| Flat (E.B) | £25 |

Ti o ba nfe okan ninu awon ile wonyi yara tete lo ri Ogbeni ODUS:— 187 Bamgbose Street Lagos. ni deede agogo merin irole si agogo mefa irole ijafara lewu anfani nla kan ni eyi je fun o pe o ri ile l'Eko

# Kereo Kere o Akiyesi Pataki




Awa na le jeri wipe Ojulowo hanuhanu Egbogi LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pelu meji re ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ile Naijiria

A wa na njewo ni igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lenu gbogbo enia tomode t'agba ni asiko yi ti nwon fi se oro ati orin larin ara won nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwon npe ni LEOPILLS

Imoran awon Dokita Oyinbo ti nwon nse iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan so wipe bi o ti lagbara to ati bo je Ojulowo giriki ati atamatase fun "JEDIJEDI" bi o tiwu ki ojo re pe to be na ni nwon si tun fi owo soya tabi pe iledi fun gbogbo awon ti amodi tabi iju, Igbe sise, aiko ri igbonse deede, inurirun n'gbakugba ara wiwo, Esaori ehin didun sisan ati aiko riran kedere ko doro buruku lara, aisan Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pel

"Wipe nwon yio ri alafia ni kiakia ti nwon nba egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun eje se enia nipa sis di otun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ORO IJAFARA SI LEWU PELU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla sile mefa abo (6/-6 pere Igo kekere sile meta abo (3/6) pere. Ber Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi A nta ti e ba fe n Sobu awon:—

WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palm Church Street. Phone 22787

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos

ATI NI SOBU
IŞE OLODUMARE DISPENSARY OKE BOLA IBADAN
ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

# Enia Dudu Ti o Koko Joye Adajọ Nilu Eko Ni Daddy White

Nigba aiye ọba Dosunmu, Oyinbo Ajẹlẹ agba ranṣẹ pe ọba Eko ati awon enia nwanyi bi Anduru, Jele, Ọṣọla, Peni, Macualay, White Ọbasa, Ajasa, Asọmu sọun ati awon enia jankan-jankan bawọn ni, o wi fun won wipe, oyẹ ki enia dudu le ma da ẹjọ ara wọn ni torina ki nwon yan ẹnikan ti o mọ ẹjọ ni dida ti osi tun gbọ ede Oyinbo wa fun on Laifa ọrọ na gun, nwon yan Daddy White ti iṣe Baba to bi Dr White ti Idita Nwon ti i bujẹ ko ile ẹjọ re si abẹ petesi to mbẹ nl Iga Iduganran n gbana

Daddy White mọ iwe o si gbọ ede Oyinbo ni ọjọ kan ọkunrin Imaro jẹ oni ṣowo kan ni igba owo ẹyọ kofẹ san owo na pada mọ ko kuku si iwe ipẹjọ ni ako ko na Ọkunrin Onişowo na lọ fi ẹjọ ọkonrin Imaro na sun ọba, ọba ranṣẹ lọpe e

Ni akoko ti nwọn aro ẹjọ yi lọwọ ni Ajẹlẹ agba wa si Iga ọba lati fi oju ri bi nwon ti nṣe ẹjọ na si Onişowo na ṣo wipe Imaro na jẹ on ni igba owo ẹyọ sugbon Imaro taku pe on kojẹ ni gbese owo kan, ti oba si dabi irọ ki nwon ranṣẹ lọpe Baba Tairu Alaje wa nitotọ nwọn ranṣẹ lope Al je na wa.

Onişowo na bọ siwaju Aje, o wipe, bi o ba jẹ wi pe okunrin Imaro yi ko jẹ on ni igba owo ẹyọ, ki aje mu on o yege, okunrin Imaro mu opa ọwọ rẹ fun onişowo o wipe ba mi gba dani na o bọ sori Aje o wipe bi o ba jẹ wipe owo ti on jẹ onişowo yi ko si ọwọ rẹ ki Aje na mu on on na tun yege Nwọn mu aje yi nigba mẹta mẹta ti ko si ẹnikan to jẹbi tabi ti o jare

Ajelẹ yi wa iwo ṣẹgẹ bi Daddy White yio ti şe da ẹjọ na nina eyi ni on yio fi mọ bi enia dudu ti I gbọn si Daddy White sọ fun Imaro na wipe ki o mu opa ọwọ rẹ wa nwọn o şẹ si meji Imaro yio mu apa kan onişowo yio mu apa keji

## Lati Ọwo

## Ẹso Ajekunlẹ

Bi nwọn ti şe opa na si meji ni owo ẹyọ ba tu da silẹ Lati ọjọ na wa ni enia dudu ti gbayi lọdọ Oyinbo.

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS Jan 22 -Feb 20) Bi o ba nfẹ iranlọwọ akoko yi lo yẹ ki o rin sunmọ awọn eni pataki lati ran ọ lọwọ.

PISCES (Feb 21 – Mar 21) Orişirişi nl işẹ ti o mbẹ fun ọ loni, mura sugbọn bi o ti şe lana ni ki o şe loni, maşe lo aseko kan danu, iwọ yio si şişẹ pupọ lowurọ yi, ki o gbidanwo lati maşe bẹ lojojumọ, ki o ba le ri aye lati gbadun ara rẹ.

ARIES (Mar 21 - April 20) Ohun kan mbẹ ti o nda ọ lokan ru, lowurọ yi laipẹ ohun na yio kuro, aş lẹ oni yio si gbadun fun ọ, larin awọn ọrẹ ati ojulumọ.

TAURUS (April 21 – May 20) Egbogi ti iwọ yio kọkọ lo ni owurọ ni yio şişẹ gbadun fun ọ, şugbọn maşe fi ara silẹ, egbogi pupọ ko le şişẹ tẹrun.

GEMINI May 21 - June 21 Asiko to dara niyi, maşe lo asiko dani aşalẹ ọjọ oni yio mirọngindin fun ọ

CANCER June 22 - July 22 Işẹ rẹ yio pọ jọjọ ni owurọ yi, şe jẹjẹ bi o ba di osan ki o şişẹ taratara, iwọ yio ri owo ati dukia lo gẹgẹbi o ti fe.

LEO July 23 – Aug 22 Iwọ yio ni itẹlọrun loni şugbọn aşeju rẹ pọju, kio lọ şe abẹwo awọn ọrẹ rẹ ni aşalẹ

VIRGO Aug 23 – Sept 23 Irọrun yio jẹ fun ọ lọjo oni iwọ ylo si ni anfani gọbọyi pẹlu bi o ba ni eto si i, ki o maşe ba awọn ẹbi rẹ şe gbolohun asọ tabi iyọ nkọ, emi nkọ.

LIBRA (Sept 24-Oct 23):-Onipọrẹ yio jẹ fun ọ ni ọsan oni, iwọ yio si ja ajabọ kuro ninu ailera ti o ti nyọ ọ lẹnu şugbọn maşe fi ikanju la ọbẹ gbigbona ohun ti o si ngbero ninu ọkan rẹ yio jẹ ire nigbati ile ba fẹ şu.

SCORPIO (Oct 24 Nov 22). Egbogi ti iwọ yio lọ ni owurọ ni yio dara jo ti ọsan lọ, nitori awọn ẹbi rẹ yio şe atako rẹ ki o maşe ba wọn gbonu.

SAGISTARIUS (Nov 23-Dec 21):—Aşiri rẹ yo bọ ọpọ awọn enia yio fun ọ ni iyọnu lati şe iranlọwọ fun ọ şe sara ni aşalẹ ko o si şe are yio dara fun ọ.

CAPRICOM (Dec 22-Jan 21):-Inu yio ma bi ọ ara yio si makan ọ nitori pe, ohun kan ti o fẹ şe ko jẹ bẹ akoko ọsan lo dara kio si lọ şe abẹwo awọn ọrẹ rẹ.

**Ha! Kini Eleyi O**




OGUN A PA YANMU — YANMU
OLORI ERIN MẸTA NI

Three elephant Brand mosquito coils dara pupọ A ni o dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ-

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia oorun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ. Bakan na ni o si tun yara pa ayan ati iden

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu Three elephant Brand coils tire loni, ki o si dan wo, iwọ yio ri bi yio ti şe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki ori daju pe ogun yanmuyanmu olori erin mẹta yi ni nwọn mu fun ọ

Three elephant mosquito Brand coils yi wa ni şọbu ati ile itaja kakiri orilẹ ede yi.

*DISTRIBUTORS*

**Amos GBEMLE & BROTHERS**

34, Docemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street. West
LAGOS

# Alaye Ọro Lori Rudurudu Ipinlẹ Iwo Orun

**Lati Oju Ewe Keji**

Ẹjẹ ki a vo awọn ọna wọnyi' ninu awọn ti ayan bi alabojuto (Commisson) idido ni Awon ẹlẹkọ nla wa bẹeni Dokita ẹlẹ ọ wa ninu wọn Nigbati n kan da ru ai iwọ ojun ko si ẹnikan ninu wọn to le dide gegebi olugbala ilẹ Yoruba ki won tẹ waya si Ogbẹni Esua ni Eko tabi ki wọn sọ fun Olọtọ kan ni gbogbo ilu Yoruba li oba i ,ọmọwe, bi oṣelu wipe aiye nbajẹ lọ

Ki wọn pe awọn bi Ọlọla Ademọla, bi Majekodunmi, bi Kofo Abayomi ni Eko ati bi ọba Oni ti ile Ifẹ, Ọlọpa ati awọn jankan jankan bẹ lọ, titi awon kan npadanu ohun ini wọn.

Ti Ọloto ko le rin ni gbẹfẹ ni ita. Ti a nha awon enia mo ile gbohun kan lati ẹnu awọn ti ayan bi olọtọ idibo Iwo Orun.

Ha! Gbogbo nkan wọnyi ni alabojuto idibo sefun ida gbasoke Ilẹ Yoruba, Ro re ti o ba tọ bẹ a bi ko to bẹ

Bi Ọgbẹni Esua ko ba pe nyin koha tọ lati kigbe fun araiye fun ijihin ise iriju nyin? Sugbon lo ni ẹ fẹ ki a wa to wa ni ita gba nyin gbo bi olotọ ki a s wa mu oloto ti ki ṣe ẹmọ nyin bi alaisoto fun otito inu rẹ

Bi mo ti nkọ we yi omije kan loju mi fun ipo ti ẹyin ọmọ Yoruba fi ile Yoruba si nitori owo ati nitori ijẹku jẹ nyin ọrọ Ọlọrun so peka wonyi ni ẹnyin se ti emi siti oini si dakẹ to naya

Ọlọrun so pe on yio bere nkan wọnni lowo oluse bu buru gbogbo Gbogbo ẹnikẹni to ba dẹṣẹ larin ilẹ Yoruba ti Ọlọrun ba si nbẹ ẹṣẹ na wo lori ilẹ na to ba yi ọjọ ibẹwo yio de

Ọrọ ikẹhin mi si nyin ni pe ọpọ ninu nyin ti lọ si Unifasiti ti Amẹrika ti Londonu, ti Germani, ati bẹbẹ lọ, ṣugbọn tani ninu nyin ti o lọ si Unifasiti ti Ọyọ Misi, ti Ẹgba Lisabi, ti Ikọle Ekiti, ti Adde Imorai?

Gbogbo ilewe Giga awọn wọnyi ni o kun fun Iwa ogbon bi ati ma ṣe ilu ti ki ibaje Nitorina ẹ ma jẹki a gbe ẹbi tiwa fun ẹlomiran ru

Ẹnyin omo otito ni o yẹ ki o mo otito ju ẹnikẹni lo Ọrọ Ọlọrun so wipe enyin o mo otito, otito yio so nyin di ominira

O digba diẹ na o



S O JAIYE

---

**Ẹ maa ka Irohin Imọlẹ Ki ẹsi maa Polowo Oja Nyin Sinu Rẹ Lojojumo**

# Ọjogbon Imo Ijinlẹ Ẹko



Aworan oke yi ni ti Dọkita V I Lenin ẹniti o gba ọpọ lọpọ oye imọ ijinlẹ ninu ẹkọ to si tun jẹ ọkan ninu awọn onimọ ijinlẹ ati amoye

Dọkita Lenin yi si tun jẹ ọkan ninu awọn ti nwon jijo ja fun ominira orilẹ ede Rosia ki nwọn to gba ominira na ni inu odun 1917

---


## ẸGBOGI JẸDIJẸDI

BERE FUN EGBOGI

**"CYCLEVEN"**

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ o si nyọ ọ lenu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu" tabi iho Idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwon nta kakiri odẹ nisisiyi ti wọn a ma polowo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la le ri mẹwa ninu ogọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara. Awọn ẹlomiran lero wipeboya bi awọn ba lọ si ile Dokita lati lo ke eyiti o ba nyo jade lati omusu ku ni: pa bẹ awon o no lowo rẹ palapata

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara: Lẹnin odun die iyonu rẹ yio si tun ma bẹrẹ bakanna, Orisirisi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbonse dede tabi lojojumo, elomiran nipa ijoko ni ojukanna selu lojojumo tabi gigun keke ylogere (Basikulu) pupo elomiran ewe nipa ije Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupo ju. Jedijedi orisirisi ni o wa ewo ni tirẹ? Bi o ba nyo jade ninu olusu tabi ti o ba nmu wa lẹhin igbonsẹ tabi to ba i nyo ti o ba ṣe igbonsẹ tan ni, tabi ti nrin o ninu omusu ni eyikeyi ti o bara bere egboki "CYCLOVEN" ti awon Oyinbo Jamani fere wa idi rẹ ko ki o si danwo orisi meta ni o dalu wipe iwo yio bo lowo Jedi patapata alafia y'o de si ekeji re ko si ninu gbogbo egbogi sa Igboro ilu Naijiria Bere re ni:—

Waterloo Medecine Store
8, Palm Church Streer Lagos,
Phone 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

